# ỌLỌRUN GBEJA IRANṢẸ RẸ: AṢIWAJU ISRAẸLI
## Numeri 17:1-13
### ẸKỌ 106 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Ki iṣe ẹnyin li o yàn mi, ṣugbọn emi li o yàn nyin, mo si fi nyin sipo, ki ẹnyin ki o le lọ, ki ẹ si so eso, ati ki eso nyin le duro" (Johannu 15:16).**

**I Awọn Ọpa Aṣoju**

1. Olukuluku awọn ijoye tabi awọn olori ile Israẹli mu ọpa ti rẹ̀ wá, ọpa mejila, Numeri 17: 1, 2, 6; 1:5-16
2. A kọ orukọ olukuluku si ara ọpá rẹ̀, gẹgẹ bi ile awọn baba rẹ̀, Numeri 17:2
3. A kọ orukọ Aarọni sara ọpa ti idile Lefi, Numeri 17:3
4. A fi gbogbo ọpa naa lélẹ̀ ninu Agọ-ajọ niwaju apoti ẹri naa, Numeri 17:4, 7

**II Ọpa ti O Rúwé, Dídá Aarọni Lare**

5. A ṣe idanwo yii ki a ba le dá kikun awọn Ọmọ Israẹli lẹkun, Numeri 17:5; 16:41-50
6. A mú awọn ọpa naa wá ni ijọ keji, ọpa Aarọni ti rudi, o si tanna, o si so eso almondi, Numeri 17:8
7. A fi awọn ọpa naa hàn fun gbogbo awọn Ọmọ Israẹli, olukuluku si mú ọpa ti rẹ̀, Numeri 17:9

**III Ọpa Aarọni, Ẹri Iyebiye**

8. Ọlọrun paṣẹ fun Mose lati mú ọpa Aarọni pada wá siwaju Apoti Ẹri lati fi pamọ bi àmi fun awọn ọlọ̀tẹ naa, Numeri 17:10; Heberu 9:4
9. Mose si ṣe bẹ̃: bi OLUWA ti fi aṣẹ fun u, bẹ̃li o ṣe," Numeri 17:11
10. Awọn Ọmọ Israẹli ri aṣiṣe wọn nikẹyin, wọn ko si tún kùn mọ́ lori ọran yii, Numeri 17:12, 13

## ALAYE

**Awọn Alariwisi Eniyan**

A maa n sọ pe, "A ki i fẹ́ iṣẹ iyanu kù nibi ti o ba yẹ lati ṣe iṣẹ iyanu." Bi ẹni kan tabi awọn eniyan diẹ ba wà ti wọn ba jẹ́ oloootọ ninu iwadi wọn, Ọlọrun kò ni kuna lati fun wọn ni idahun si ibeere wọn. Jesu wi pe, "Bi ẹnikẹni ba fẹ lati ṣe ifẹ rẹ̀, yio mọ̀ niti ẹkọ́ na, bi iba ṣe ti Ọlọrun, tabi bi emi ba nsọ ti ara mi" (Johannu 7:17). Ọlọrun ko fẹ ki a wà ninu iyemeji; ni akoko ti o ba si wọ̀, Oun yoo fi ara Rẹ̀ hàn fun wa gẹgẹ bi O ti ṣe fun Tọmasi.

Ni akoko yii, awọn Ọmọ Israẹli wà ninu iyemeji. A ti bori iṣọtẹ Kora, Datani ati Abiramu nipa ọwọ́ agbara idajọ Ọlọrun. Ọlọrun ti fi hàn kedere ẹni ti Oun yàn nipa titẹwọ gba Aarọni ni ti ọran fifi turari jona lẹnu ọna Agọ (Numeri 16:16-18, 35). Awọn ọlọtẹ naa ti funrugbin aini-iṣọkan silẹ laaarin ijọ, awọn eniyan naa si dabi ẹni pe wọn ṣi n jiyàn ẹni ti i ṣe aṣoju Ọlọrun tootọ. I ba ṣe pe awọn eniyan naa ti ronu lori gbogbo ohun ti Aarọni jẹ́ ninu iṣẹ-alufaa naa wọn ki ba ti ṣe ariwisi ipè rẹ̀ si ipò naa. Nigba ti ajakalẹ-arun naa bẹrẹ laaarin awọn Ọmọ Israẹli nitori ọtẹ ati kikun wọn lori ọran yii, Aarọni sure lọ saarin ijọ pẹlu awo-turari ni ọwọ́ rẹ̀ lati ṣètutu fun awọn eniyan naa. Oluwa yẹ́ ẹ̀bẹ̀ ati adura Aarọni sí, a si dá iyọnu naa duro. Bi Israẹli ko ba ni ẹri miiran, iṣẹlẹ yii to fun ẹri pe Aarọni ni ẹni ti Ọlọrun yàn fun iṣẹ-alufaa.

**N Fẹ́ Iru Eniyan bi Aarọni**

Lai si iranlọwọ Ọlọrun kò si ẹni kan ti o le ṣe ohun ti Aarọni ṣe. Eyi ni ẹri tootọ fun ipo alufaa Aarọni – agbara fifi turari jona lati dá ajakalẹ arun naa duro nipasẹ eyi ti a fi mọ̀ pe Ọlọrun gba a gẹgẹ bi oluṣipẹ fun awọn eniyan naa. Jobu wá irú abanibẹbẹ bẹẹ, ṣugbọn kò rí. Ni akoko ti Esekiẹli, Oluwa "wá ẹnikan lãrin wọn, ti ibá tun odi na mọ, ti ibá duro ni ibiti o ya na niwaju mi fun ilẹ na, ki emi má bà parun: ṣugbọn emi kò ri ẹnikan" (Esekiẹli 22:30). Irú eniyan bi ti Aarọni ko wọ́pọ̀ mọ bi awọn kan ti n fẹ fi ye wa pe wọn pọ̀; ṣugbọn lai ṣe aniani a n fẹ iru awọn eniyan bẹẹ ju ti atẹyinwa lọ.

Awọn eniyan Israẹli gbèrò gẹgẹ bi ọrọ Kora pe "gbogbo ijọ li o jẹ́ mimọ́, olukuluku wọn." Nipa idajọ Ọlọrun ti o yara kankan lori awọn ẹlẹṣẹ naa, wọn wa ri i pe wọn ti ṣina. Igba gbogbo ni Oluwa fẹ awọn eniyan ti yoo duro laaarin meji awọn alaaye ati oku bi ti Aarọni, ti wọn yoo maa bẹbẹ fun awọn ti o ṣi wà laaye. A pè wa, gẹgẹ bi Onigbagbọ lọjọ oni, lati maa bẹbẹ, ki a maa gbadura, ki a si maa ṣipẹ fun gbogbo eniyan (1 Timoteu 2:1). A ṣe wa ni "awọn ọba ati awọn alufa fun Ọlọrun"; nitori naa ojuṣe wa si Ọlọrun tobi. Iṣẹ titan Ihinrere ti igbala kalẹ kò pari si ọdọ awọn

alufaa wa nikan; o jẹ́ iṣẹ́ olukuluku ọmọ Ọlọrun “ti a tunbi.” Lẹyin ti a ba ti fún Irugbin naa, o jẹ iṣẹ wa lati bomirin in nipa adura wa ki o ba le dagba soke si iyè ainipẹkun ninu ọkàn awọn ti o n gbọ́ ọ.

**A Ṣe Iṣẹ-iyanu Kan**

Ọgunlọgọ awọn eniyan ni wọn lọwọ ninu iṣọtẹ Kora. Awọn aadọtalerugba (250) ijoye ti o lorukọ ti wọn sowọ́ pọ̀ pẹlu rẹ̀ jẹ awọn eniyan ti a pọ́nlé pupọ. Awọn ni olori awọn janduku eniyan; awọn ni wọn si ti siwaju lati tako agbara ti Mose ati Aarọni fi n ṣakoso. Nigba ti a si fi iná run wọ́n lati ọwọ́ Oluwa, awọn eniyan naa bẹru, aya wọn si pami fun iṣẹju kan; ṣugbọn kò pẹ́ kò jinna ni ibẹru bojo fò lọ, ti ibinu ati irunu dipo rẹ̀, ti wọn si fi ẹsun kan Mose ati Aarọni pe awọn ni wọn pa awọn aṣiwaju wọn. Ajakalẹ-arun naa tun mu ipaya ba ọkan wọn; ati pe nisisiyii ki wọn ba le ni àmi ti o ṣe e fi oju ri ti o si le wà pẹ́ titi ni iranti pe Mose ati Aarọni ki ṣe eniyan ti n fi agbara gba ipo ti ki i ṣe ti wọn, ṣugbọn pe wọn jẹ ẹni ti a yàn lati ọwọ Oluwa, a ṣe iṣẹ-iyanu ti ọpa yii.

Nipasẹ Ọrọ Oluwa, Mose paṣẹ fun awọn Ọmọ Israẹli lati mu ọpa kọọkan wa gẹgẹ bi ile awọn baba wọn, ọpá mejila gẹgẹ bi ẹya wọn. Awọn ijoye tabi awọn olori awọn ẹya naa ni lati mu ọpá wa pẹlu orukọ olukuluku ni ara ọpá ti rẹ̀. Awọn ọpá mejila naa pẹlu ọpá Aarọni laaarin wọn ni a fi lelẹ niwaju Oluwa ninu Agọ ẹri naa. Ileri Oluwa ni pe, “Yio si ṣe, ọpá ẹniti emi o yàn yio ruwe.” Nigba ti Mose wọ inu agọ́ ẹri lọ ni ọjọ keji, ọpá Aarọni fun ile Lefi ti rudi, o si tanna, o si so eso almondi.

Kò i ti si igba kan ti ẹri iṣẹ-iyanu kan kun rẹ́rẹ́ to bayii rí. Ohun gbogbo nipasẹ rẹ̀ kọja agbara ẹda to bẹẹ gẹẹ ti ko fi si iyemeji ninu ọkàn awọn eniyan naa tabi awọn ijoye naa ti n jowu ni ti pe Ọlọrun ni o yan Aarọni, ati pe Ọlọrun lọwọ si ọran yii. Ki a wo ẹka igi kan, ti a ya kuro lara odindi igi, lai si eepo tabi omi lara rẹ̀, ti a si fi lelẹ ni ibi gbigbẹ kan fun alẹ ọjọ kan pẹlu iru awọn miiran bẹẹ -- ki a si wa ri ẹka-igi naa ki o wá gbé awọ igi tutu minimini wọ̀, ki o rudi, ki o tanna, ki o si so eso jade nigba kan naa – eyi yoo jẹ ifihan abami nipa ti igbeja Ọlọrun lati mu iyemeji kuro, ati lati pa gbogbo awọn alariwisi lẹnu mọ́. Gbogbo awọn Ọmọ Israẹli ni o yẹ awọn ọpá naa wò, olukuluku ijoye ni o mu ọpa ti rẹ̀. Bayii ni Ọlọrun fi idi oye alufaa Aarọni mulẹ ni igba mẹta ọtọọtọ: lẹẹkinni nipa ororo ati ẹ̀jẹ̀; lẹẹkeji nipa iná, ati nikẹyin nipa ọpa ti o rudi. Awọn eniyan wọnyii, nisisiyii, wa fara mọ eto Ọlọrun, wọn gbé jẹẹ, wọn kò si tun kùn mọ nipa awọn ti i ṣe alaṣẹ wọn.

**Ọpa Aarọni, Ohun Iranti Titi Lae**

Ki a ba le mu un da atirandiran awọn Ọmọ Israẹli ti n bọ̀ lẹyin loju nipa ẹni ti Ọlọrun yàn, ati lati fi ṣe àmi fun awọn ọlọtẹ wọnni, Oluwa sọ fun Mose pe ki o mu ọpa ti o rudi naa pada wá si àye rẹ̀ niwaju Apoti ẹri. Mose si ṣe bẹ̃: bi OLUWA ti fi aṣẹ fun u, bẹ̃li o ṣe.” Nisisiyii, awọn eniyan naa ti ni ẹri ti o hàn gbangba nipa ẹni ti Ọlọrun yàn si ipo alufaa. Awọn Ọmọ Israẹli ri ipo ti wọn wà niwaju Ọlọrun, wọn si wi fun Mose pe, “Ẹnikẹni ti o ba sunmọ agọ́ OLUWA yio kú.” Dajudaju wọn ri ara wọn gẹgẹ bi Ọlọrun ti ri wọn. Ẹṣẹ wọn pọ̀ rekọja loju wọn, wọn si woye pe ẹ̀yìn ko ṣe e pada si. Bi awọn eniyan naa ba kugbu wá si Agọ Ajọ, tabi bi wọn ba tun wa pẹlu ọkàn ati gba ipò Aarọni, kikú ni wọn yoo kú. Ṣugbọn bi wọn ba wá gẹgẹ bi ilana Ọlọrun, ki i ṣe pe wọn ni ẹtọ lati wá nikan, ṣugbọn wọn ni ireti ati ri ibukun Ọlọrun gbà nipa ṣiṣe bẹẹ.

**Ọpa Naa Lonii**

Awọn ẹri ti Ihinrere Jesu Kristi ni a le fi we ọpá Aarọni. Jesu ni Olori Alufaa wa, O si mu Ihinrere ti Ijọba naa wa si ayé gẹgẹ bi ọpá agbara Rẹ̀. O jẹ ọpa alade ti o n gberu nigba ti O wà laye ti O si n rin kaakiri lori ilẹ; ṣugbọn nigba ti O kú lori igi agbelebu ti O si lọ sinu iboji, awọn ọta Rẹ̀ ro pe Ihinrere Rẹ̀ ti ba A lọ. Ireti iye ti o wà ninu ọkàn awọn ọmọ-ẹyin Kristi dabi ẹni pe o ti ṣákì. Awọn ọta Kristi paapaa ni ero kan naa ninu bi awọn Ọmọ Israẹli ti o kùn – pe Kristi ki I ṣe ẹni ami-ororo Oluwa.

Iru iṣẹgun nla wo ni eyi ni nigba ti Jesu jinde! Ihinrere, ipá agbara Rẹ̀, tun pada wa lọtun, lati rudi, lati tanna, ati lati so eso. Lẹẹkan si i, iroyin ayọ̀ ti Ihinrere igbala tun lu agogo lookan àyà awọn eniyan. Ireti aaye tun sọji ninu ọkàn awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. Wọn ti lọ kaakiri, wọn n waasu Ihinrere; ibisi iṣẹ naa ko si ni oṣuwọn. Lonii a wà ni akoko ipeéṣẹ́ ibisi Ihinrere; ṣugbọn ọpẹ ni fun Ọlọrun! A ṣi le ṣiṣe fun Un ninu ọgba ajara Rẹ̀. “O si wi fun wọn pe, Ikore pọ̀, ṣugbọn awọn alagbaṣe ko to nkan: nitorina, ẹ bẹ̀ Oluwa ikore, ki o le rán awọn alagbaṣe sinu ikore rẹ̀” (Luku 10:2).

Gẹgẹ bi ọpá Aarọni ti o rudi ti mú opin wá si kikùn awọn Ọmọ Israẹli lori ọran yii, bẹẹ sá ni Ihinrere “pe ni rere iṣe. . . . . . dá òpe awọn wère enia lẹkun” (1 Peteru 2:15).

A fi ọpá Aarọni pamọ gẹgẹ bi ami ijolootọ Ọlọrun si eniyan. Ni aye ode oni, kò tun si àmi ifẹ Ọlọrun si araye ti o ga ju Ihinrere Ọmọ Eniyan. Ihinrere yii kọ́ wa ni ọrọ ti o le yé wa, “Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun” (Johannu 3:16).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o gba ọpá kọọkan lọwọ awọn ijoye awọn Ọmọ Israẹli?
2. Bawo ni a ṣe mọ awọn ọpá naa yàtọ̀ si ara wọn?
3. Orukọ ta ni wa lara ọpá fun ile Lefi?
4. Nibo ni Ọlọrun wi fun Mose pe ki o kó awọn ọpa naa sí?
5. Ki ni iwọ ro pe o jẹ eredi ti Ọlọrun fi n fẹ wọn nibẹ?
6. Ki ni ṣẹlẹ nigba ti Mose yẹ awọn ọpá naa wò ni ọjọ keji?
7. Njẹ iru nnkan bayii le ṣẹlẹ rara nipa ẹda?
8. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe nigba ti wọn ri awọn ọpá naa?
9. Ki ni Mose ṣe pẹlu ọpá Aarọni? Ki ni ṣe?
10. Njẹ awọn Ọmọ Israẹli mọ iduro wọn pẹlu Ọlọrun ni akoko yii?